# B'OLUBADAN BA KU TANI YIO J'OYE ?


AWOGBA
Olodumare
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St.,
LAGOS



ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



TO CLEAR
Brown, Black & Grey
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
LAGOS


VOL. VII No. 447. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 24, 1955. KỌBỌ MEJI (2d.)

## B'Olubadan ba ku tani yio j'oye?

IBADAN. Awọn agba Ijoye ilu Ibadan yio yan enia si ipo Ọtun Balogun Ibadan to ku laipẹ yi, bi ero wọn ba papọ gẹgẹbi a ti gbọ wipe yiyan enia si aye na ni lati jẹ ọkan ninu awọn Ijoye ti ijọ Balogun Ibadan

Awọn Ijoye Balogun ti nwọn ni lati mu ọkan ninu wọn niwọnyi:- Oloye Aderọgba, (Osi Balogun) Oloye Ṣọlagbade (Aṣipa Balogun) Oloye Ogunṣọla (Ẹkẹrin Balogun.)

A si gbọ wipe awọn agba Ijoye ti wọn yio ṣe ipade yan enia na ti ri iwe gba wipe ki nwọn maṣe ro oye na si awọn I j o y e meji ti nwọn ṣe atilẹhin fun Ologbe Oloye A k i n y ọ nigbati o ndu lati jẹ Olubadan, awọn meji na ni Oloye Aderọgba ati Ṣọlagbade, Osi ati Aṣipa Balogun, nitoripe n w ọ n ti huwa ti o lodi si aṣa ibilẹ Ibadan l'ọna ifinijoye.

## Odun Keresimesi wo'le de

Ni iwoyi ọla, gbogbo ilu wa, ani, gbogbo agbaiye ni yio ma dun y u n g b a fun aya'jọ iranti ọjọ ibi Olugbala araiye, Jesu Kiristi, Olukọni nla ti ko ni afiwe.

Awa Eleti-ọfẹ fi eyi ki ẹnyin ọkawe wa, Onibara wa jake-jado Nigeria ati ni Oke-okun (Gold coast) ku ewu ọdun, ẹ si ku iyedun o.

Ki Oluwa ṣe ọdunni ni rere fun wa.

Ọdun owo, ọdun ọmọ, ọdun alafia, T'owo-t'ọmọ l'Ọpẹ nso, ki owo rere ya sile gbogbo wa o.


## THE NATIONAL BANK
### Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati
di onișowo nilẹ Nigeria wa,
ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimọye awọn onișowo ilẹ Nigeria lara,
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—

37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Mase Ta Elewon L'ore, Ese Ni

AGBOR Ẹnikan ti orukọ rẹ njẹ D a v i d Michael ni Adajọ fi s'ẹwọn oșu mẹta, nitoripe o fun ẹlẹwọn ni owo șile kan

Michael sọ fun adajọ wipe anu l'o șe on, ti on fi fun ẹ l ẹ w ọ n na lowo, on ko si mọ wipe ẹșẹ ni lati șe bẹ.

Awọn o l u șọ ẹ l ẹ w ọ n (warders) mẹta ni o jẹri tako ọkunrin yi. Ẹnyin enia wa, ẹ fi eyi kọgbọn o.



## Western Regional Legislature

VACANCY FOR SECOND CLERK

Applications are invited from suitably qualified Nigerian candidates to fill a vacancy in the pensionable post of second Clerk of the Regional Legislature.

Particulars of the post are as follows :-

SALARY SCALE - A. (i.e. £624 x 36-£696; £804 x 42-£1,140 x 48-£1,380).

QUALIFICATION REQUIRED Applicants should be male and will not be appointed unless they are qualified to practise as a barrister, an advocate or solicitor in Nigeria, England, Scotland, Northern Ireland, any British Dominion Colony or protectorate or the Republic of Ireland.

DUTIES OF THE OFFICE: The Officer appointed will be required to assist in the preparation of papers relating to Legislation, questions and motions for both Houses of Regional Legislature, in the control of the expenditure on the services of the Legislature, in the preparation and publication of the Official Report(Hansard) and other official papers, and to perform such duties as the first Clerk may assign to him from time to time. He will have to attend the meetings of the Regional Legislature and will be expected to acquire a detailed knowledge of Parliamentary practice and the Standing Orders of both Houses.

MEDICAL EXAMINATION : The selected candidates will be required to be passed medically fit by a Government Medical Officer.

METHOD OF APPLICATION : In Nigeria: Applications from candidates not in Government Service should be completed in duplicate on the prescribed form obtainable from the Secretary of any of the Region or Federal Public Service Commissions. Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Heads of Departments and be accompanied by copies of Confidential Reports for the last three years and a covering letter wherever possible containing special Comments that may prove of value in assessing the suitability of the candidate for post applied for.

IN THE UNITED KINGDOM : Applications should be Completed in duplicate on the prescribed form obtainable from the office of the Commissioner of the Western Region of Nigeria, 18 Grosvener Gardens, London, S.W. 1, and submitted through the Liaison Officer to reach him by December 28, 1955.

All applications should reach the office of the Director of Recruitment, Public Service Commission, Western Region of Nigeria Ibadan not later than 2nd January, 1956

## NIGERIAN RAILWAY CORPORATION

### Idaduro oko ile ti yio ma ko ero wa woko Ilu Oyinbo

A ti gba ni ero lati bere si ma fi Ọkọ-ilẹ (Boat Train) ko ero lati ilẹ Hausa, Kano, ati Jos wa wọkọ oju-omi ti ilu Oyinbo ni Apapa ni ọjọ kini oṣu January, 1956. Ṣugbọn nigbati awọn Ọkọ ti a ranṣẹ fun ko tete de lati ọdọ awọn ti n nse (Manufacturers) a ni lati da duro di ọjọ kọkandinlogun oṣu February, 1956, ki o to bẹrẹ.

**R.B. Emerson**

**Oga Ile-Ise Oko-Ile**

## Salawu Aremu Komo Jade

Salawu Arẹmu ọmọ ilu Omupo se ikọmọjade ọmọ tuntun ti Ọlọrun fi ta lọrẹ on ati aya ni Olawole ni ọjọ atalata tokọja yi.

Dowọle aya Falokun fi ilu gangan pitu n'bi ikomọ na Baba ọmọ titun si fi jije ati mimu su gbogbo enia to pe sibẹ. A sọ ọmọ ni Sikiratu Abeni. Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn enia ti o peju pase bi awọn ọgbeni Lawal Ẹkundayọ, Shute, F. A. O Yinusa Yesufu Amuda Jimoh David-Mẹmudu Oke ati awọn bẹb.

Ọlọrun ko ṣe ọmọ na ni alarubarika.

## Aremo Oba Alafin Ku S'ehin Odi

EKO, Arẹmọ Ọba Alafin Ọyọ, Adebayọ Adeyẹmi ti o ti wa ni ipati lati aka i bi ọdun m ji sẹhin, ni a gbọ pe o ku si ile rẹ ni Ijọra, l'ọna Apapa l'oruma ju ọjọ ọsẹ (Sunday) to kọja.

A si gbọ wipe nwọn yio gbe oku rẹ ọ siu si Ọyọ ni ọjọ Wednesday ọsẹ yi nwọn ni Arẹmọ to ku yi ko ṣe amodi ti ọlọjọ fi de ba l'ojiji.

Lọwọ iku ojiji Oluwa rere gba wa.

## Western Region Production DEVELOPMENT BOARD

VACANCY FOR PHARMACIST

The Board invites applications from suitably qualified candidates for the post of Pharmacist.

Candidates should have received a sound general education and must be registered Chemists & Druggists, with considerable years of practical experience.

Selected candidate will be responsible to the Bord's Medical Officers in supplying drugs and dressings to the Projects, compounding of drugs, keeping of medical stores and may have to visit all dispensaries occasionally for the purpose of stock-taking.

Salary will be in the scale £570 x 30-£750 per annum, point of entry depending upon candidate's qualifications and experience.

Applications in applicants' own handwriting, stating qualifications, experience and age, should be addressed to the Personnel Secretary, Western Region Production Development Board, Secretariat, Ibadan, to reach him not later than 4th January, 1956.

## ORIKI BAMWO




Bamwo de,, alajẹla ọmọde, agb'ọmọla bi oriṣa, akọkọluko ogun nda'mọ l'ẹkun igbona, ajata ogun ti np'otutu rọ wa-rawara, a jẹ bi idan, a gba bi etu ibọn. O s'abiku dikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nhebin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aipori ri i d'ẹkun lyọnu. Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ orin, o kapa inu iwọ, o lu jẹdi l'afupe, gbogbo abiyamọ nyọ sẹsẹ, Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o na'gbe bo'ra. Eyi npa'lẹmọ lodilẹsọ, Ọrẹ ikoko, kọṣemani awọn abiyamọ, eni araiye ojijadu ra.

O de'lu Ibo, o dọ'ga, o de'le Hausa, o d'ọba. Gbogbo Onilẹ́gmo l'o sọ pe ko l'ẹgbẹ, gbogbo ọmọde l'o nfẹ ọ fun'lera.

IGO KEKERE 2/6d.
IGO NLA 4/6d.
owo ọkọ 1/6d fun igo kan.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street,
P. O. Box 2,
Ebute-Meta.

## Irora Ibadi

Egbogi ti a ṣe fun niyi:-
Nigbati ibaradi ba odun ni, oluwa re ife itoju bi a ko ba tete fi egbogi re ko loju, aisan yi a mu fa Ehin-didun, Lakuregbe, Wodi-wodi, Akọ Ẹsanri ati Igunfọ-buruku wa.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba ṣise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danw lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

## We Protest

We the Executive Members of the Action Group, Jebba Branch, with due deference beg to register our protest against the Motion which honourable D. K. Olumofin N.C.N.C Opposition Member of the Western House of Assembly moved in the Session of the Western House of Assembly. The motion in question reads "Calling the Western Nigeria Government to institute an independent commission of inquiry into allegations of bribery and corruption in the Region.

We wish your honour to discountenance this motion because it is ill-conceived, unwarranted prejudical and provocative and motivated by ill-feelings. The mover intends to use the motion as a camouflage to distract the attention of the Westerners from the news of allegations of bribery and corruption alleged against the leaders of the N.C.N.C. in the Eastern Region and to confuse the issues in order to discredit the Action Group good Government. We vehemently protest against this motion.

We re-affirm our confidence and trust in the leadership of our leader and premier Honourable Cheif Obafemi Awolowo and his assistants.

(Sgd.) M.A. Bajomo. Secretary
" S.I. Osungbowun Chairman

## Dokita Fihan Wipe

**Ọse Palmolive Le Jeki Oju Re Dara**
LARIN ỌJỌ MERINLA



**Ara mi jolo o tun jide, Nisisiyi ti mo tele ilana**

**Palmolive**

Iba ohun ti Iwọ yio ṣe niyi :-
1. Fi ọṣẹ Palmolive wẹ oju
2. Fi hiho rẹ pa oju fun iṣẹju kan
3. Fi aṣọ nu kuro ṣe bẹ nigba mẹta lojumọ fun ọjọ mẹrinla.




EPO ILẸ AFRIKA
NI A FI ṢE ỌṢẸ YI

GOLCATE PALMOLIVE SOAP

## Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti—Ọfe

# ELETI ỌFE

A-NIU-WỌN KO SE WI L' EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 467 — "ELETI - ỌFE LAGOS" Phone 23370

VOL VII NO 447. LAGOS, SATURDAY DEC. 24, 1955.


## KERESIMESI Ọdun DE!

Lẹkansi a tun ngb'orun ọdun ariya ọjọ ibi Kristi Jẹhinkule, ki a si to ri ọsẹ kan si i, ti Eleti-Ọfẹ korikesun yin yio tun jade, ọdun Keresimesi yio ti de, yio si ti si ọkọ rẹ lọ. gẹgẹbi ẹgbagbeje awọn ọdun ẹlẹgbẹ rẹ ti fi igbakan bọ wa wo nihin ati kakiri ni gbogbo agbaiye.

Tani ninu ọgọrọ Onigbagbọ ti ko mọ adun ẹkọ ati ọrọ iyebiye ti a ri ka ninu Iwe mimọ Bibeli ti o jẹ wipe o ti ẹnu Olukọni nla na jade, ani Jesu Kristi? ko si; fun iwọn ọdun mẹta ti o fi njiṣẹ ti a ran lati ode ọrun fun awọn enia ti wọn wa ni akoko tirẹ. A koti ti asiko kan ti ọrọ aṣiṣọ jade lẹnu rẹ ri, nigbati o ka nla alaye ọrọ fun awọn ti nwọn nwa s'ọdọ rẹ, ibaṣe ọrẹ tabi ọta.

Gbọ irufẹ ibere agbanimọba ti awọn mọnafiki enia bere lọwọ Kristi, ti o si fun wọn ni idahun ti oyi fi bo awọn amọni-ṣeni enia na, nwọn bi lere wipe, njẹ o tọ ki a san Owo ode fun Kesari tabi ko tọ? ọrọ pọ nibẹ, ṣugbọn nibẹ ṣoki, o sọ fun wọn wipe, ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari ati ohun ti iṣe ti Ọlọrun fun Ọlọrun,

Iwọ ọrẹ mi, njẹ bi a ba bi ọ lere wipe, kini a nsan owo omi fun Ijọba si, njẹ irẹjẹ ha kọ ni eyi jẹ? iwọ ko ha n fi aiṣe lakaye f'ẹnu kọ bi? tabi ki o fesi ti a le fi ba ọ ro'jo wipe o ta kọnrangbọn si Ijọba ?.

Irufẹ ayajọ ọjọ ibi awọn ẹni nla bayi ko le ṣe kio ma wa ni iranti wa l'ode aiye, A dupẹ atun ọpẹ da fun idasi ti a ri lọwọ Olodumare ti o si mu wa di akoko yi. Ki Ọlọrun ninu anu rẹ maṣai ma pawa mọ l'abẹ a bo rẹ, ki Baba fi ṣiṣọ rẹ ṣọ wa karikari o. Lẹkansi, a ki ẹnyin ọkawe wa nibi gbogbo.

Ẹ ku ewu ọdun o!!!


## ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI yika Nigeria

KOSEMANI lo jẹ fun ilekile Fun orisirisi AILERA, atata Gbogbonse lo jẹ.

RA IGO KAN LONI nitori AJEBIDAN ni

LOLO

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES

Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.


No. 149

## PUBLIC NOTICE

MYOHAUNG DAY SERVICE TO BE HELD IN THE CATHEDRAL CHURCH CHRIST ON THE 29TH JANUARY, 1956, TO BE ATTENDED BY HER MAJESTY THE QUEEN AND HIS ROYAL HIGHNESS THE DUKE OF EDINBURGH

A number of tickets for this service have been allocated to ex-servicemen.

Any ex-serviceman who wishes to attend should apply in person together his discharge book or other means of identification to the Headquarters, N.E.W.A. 20 Campbell Street, not later than the 12th January, 1956.

A committee of ex-servicemen will then consider all applications and successful applicants will be issued with the necessary tickets and instructions.

Civilian dress, decorations and medals should be worn on this occasion. The co-operation of employers in facilitating applications is sought.

150

## PUBLIC NOTICE

MYOHAUNG DAY SERVICE SUNDAY 29TH JANUARY, 1956.

LINING THF ROUTE

It is proposed to line the route from Government House to the Cathedral along the Marina by ex-servicemen when Her Majesty the Queen and His Royal Highness the Duke of Edinburgh proceed to the above service on Sunday 29th January.

all ex-servicemen who wish to take part should report to the Headquarters, N. E. W. A, 20, Campbell Street or to the Secretary-General of the Supreme Council of ex-servicemen, 62, Queen Street, Yaba, together with their discharge b o o k s or other means of identification BEFORE THE 7th JANUARY, 1956, when passes and full instructions will be issued.

when lining the route, civilian dress and decorations and Medals will be worn.


## E S'AKIYESI

IGBADUN-OMODE

AWOGBA FUN OMODE



The Celebrated Fever Mixture and Infants' Preservative

Prevents Sickness, Cures Measles, Fevers, Gripes etc etc.

Sole Proprietors

PHILIP GBENLE & BROTHERS

6 Balogun Street West LAGOS NIGERIA

ORIKI IGBADUN ỌMỌDE

Njẹ o ti ra Igbadun Ọmọde fun ọmọ rẹ bi? Ogun pataki fun iwosan ọmọde.

Awo ọmọ bi Olodumare, ogun ti abiyamọ ko ri ti o nba ninu jẹ. Abiyamọ ri tan o ndunnu; baba ọmọ bu s'ẹrin.

Igbadun ọmọde ti o ma nda Abiku ọmọ lẹkun anku. A fi gbogbo ile ṣe ọmọ wẹrẹ. Ko ṣe mani fun awọn Abiyamọ ni ogun igbadun ọmọde yi jẹ. Tete sare lọ ra igbadun ọmọde ki o bẹrẹ si lo fun ọmọ rẹ, ọmọ rẹ yio si gbadun.

24/- fun mejila (dozen.) 2/6d fun ọkan each.

LILO OGUN NA :-

Ṣibi imu tea kan lẹrinmẹta lojojumọ.

IṢẸ RẸ :-

Iba, ọrẹrẹ, igbona, ọka-ori, aiperi, ebin hihu ati orisirisi arun to ma nyọ awọn ọmọde lẹnu. Tọwo, iwọ yio si ri pe rere ni Igbadun ọmọde nṣe fun ọmọ rẹ.

Iwọ le ri ogun yi ra ni gbogbo Ṣọbu ti nwọn nta ogun ni Najiria.

Wholesale Distributor :-

PHILLIP GBENLE & BROTHERS,

5 & 11, Balogun Street West Lagos Nigeria

## A Ba Olomo Yo

ABA AKODA- OYO:- Ni ojo 30. 11. 55 ni Olorun pese Omobinrin kan fun ogbeni Lasisi Olatunji Alabi ni Aba Akoda-Oyo Oruko Iya omo na ni Nusiratu Abegbe

Igbati odi ojo kejo (7. 12 55 ) Ni won ko omo na jade, ti won si fun ni Oruko yi: Awawu Aduke. Ki Olorun je ki a mo mo Oruko, Amin.

Ojo kan ni ojo Ikomo jade yi je. Orisirisi Onje ile Yoruba (Iyan, Oka, Eko) Bakanna ni oti: bi bia, emu, oti oka, awon oti lile miran pelu siga ati obi, eyiti olukuluku ba fe nlou onje ati oti ni mbere fun.

Die ninu awon enia pataki ti a le ko oruko ni yi:- Awon Ogbeni Oderinde - Akoda Oyo, Gbadamosi A k i n d e h i n-Oyo' Karimu Alebiosu, Lasisi Alufa, Anilelerin-Oyo, Tijani Raimi, Mustafa Amoo O k o Ayisatu

Awon Iyafin nlyi:- Tinuola -Ile Iba-Oyo Morawo Salsode, Afolabi Oke Afin-Oyo ati awon miran pelu. A ki gbogbo awon alabaseye ojo yi, ki Oluwa wo won po, ki o si pese ti anfani fun Olukuluku awon ti ko ri bi Amin


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J.A.AJAO BROTHERS
Medicine Store
7. Egerton Road, Lagos

## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

IKORODU
TRADING
COMPANY

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD,
IBADAN

# SIMENTI TI OYINBO BURHAM NI A FI KO



ILE EGBE KUMASI TI A NPE NI PREMPEH HALL

Ninu ile yi ni awon Igbimo Ashanti Confederacy gbe nse apejo ile yi si je okan pataki. Sibe-sibe, Simenti Oyinbo Burham ni a fi ko. Opolopo ninu awon ile nla-nla ti a ko si apa Iwo Orun ile Africa lati iwon adorin odun sehin je eyiti a fi Simenti Burham ko. O si ti se iranlowo lorisi risi ona fun idagba soke ilu nwoayi.

Eyi fi han wipe Simenti tire lo lagbara julo ti a si le gbekele kakiri agbaiye.

BURHAM
PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO
BURHAM WORKS
PORTLAND CEMENT
LONDON


## Iwe Irohin T'agba-T'ewe

Iwe Irohin Eleti-Ofe de, Oloyinmomo aka-tunka fun igbadun irohin atata

## Awo ju awo lo, enia ju enia

LATI ỌWỌ ẸSỌ IKOYI

Awo ju awo lọ, enia ju enia, lo difa fun Ajibowu ọmọ Alagbẹdẹ Oke ọna lọjọ ti gbogbo ara ndun u. Ti ko le gb'apa, ti ko le gbe ẹsẹ, a ni kio ru obukọ kan o ẹbọ, o ru lẹrinkini, on ti kalarẹ ru u, o gbe e jẹ, O ru lẹrinkeji, o gbe e jẹ, Abori Ajibowu ko ṣe pẹpẹ. Ogbe-sa". Ajibowu jẹ ijoye kan nilẹ Ẹgba nigba atijọ, ti iṣẹ rẹ jẹ iṣẹ Alagbẹdẹ ni Oke-ọna, Iṣẹ yi jẹ iṣẹ alagbara, awọn ero ti o nlọ ati eyiti o mbọ, a ma ya ni adodo rẹ lati simi, ọdọ rẹ ni awọn agbẹ ati awọn ọdẹ ima nwa fun ohun ija ati irinṣẹ wọn ṣe.

O ṣe lọjọ kan Ajibowu ko le wa sibi iṣẹ, o nṣe ojojo, ẹsẹ gbogbo awọn Onișegun lo pe, oju awọn awo pe. Amodi ti o nṣe Ajibowu yi le, bi awọn ti nṣe etutu fun aisan rẹ yi, bi o ba tuyẹ diẹ, yio tun dẹhin.

Awọn awo wariko wipe talo tun ku ti nwọn le pe si nkan yi, Nwọn lo ku Araba-Awo-ju-Awo-lọ, Awiṣẹ Ifa, nwọn ni ki o wọn lọ pe e. Awo-ju-Awo-lọ de nikẹhin. O lan Ọpẹlẹrẹ molẹ, O ri Ogbesa.

Awo-ju-awo-lo ni, bi a ba wipe ki Ajibowu ọmọ Alagbẹdẹ Oke ọna maku, Obukọ kan, ati ọgbẹsan ni ẹbọ O mu ẹbọ na ilu karagba mẹsan, o fi ori ẹbọ na ṣe ẹbọ ori, o fi ọrun rẹ ṣe ẹbọ ọrun, o mu ejika mejeji ṣe ẹbọ ejika, o fi idi okan aiya rẹ ṣe ẹbọ okan aiya, o fi ogo ẹhin, o fi orunkun mejeji ṣe ẹbọ orunkun, o fi idi ẹbọ na ṣe ẹbọ idi,.

Lẹhin ti Awo-ju-awo-lọ rubọ yi tan, ti o di ọjọ keji Ajibowu ti ko le gbe apa, ti ko le gbe ṣẹ, funra rẹ lo dide kiyan, o wọle, o wẹ ṣapa-ṣapa, o mẹkun sẹkun igke, o monun sohun lyere, o njo o nkọrin bayi pe

Ori ti nsan mi lana ko ma san mi mọ loni Asurudu Olulu, Awo jawo olulu Ọrun ti ndun mi lana ko dun mi mọ loni Asurudu Olulu, Awo-jawo-olulu Apa ti ndun mi lana ko dun mi mọ loni Aṣurudu olulu, Awojawo olulu Ẹsẹ ti ndun mi lana ko dun mi mọ oni Asurudu olulu, awo-jawo olulu.

## Ipade Babalawo Ni Ibadan Miringindin

Ibadan. Ipade oṣu mẹta mẹta ti awọn Babalawo ma nṣe, eyiti nwọn ṣe ni Ibadan ni ọjọ kẹjọ oṣu December 1955, ni dede agogo mẹwa owurọ ni ile Ọgbẹni Kasali Ojota, ni opopo Apampa ni Yemetu miringindin. O le ni ọdunrun enia to peju-pẹsẹ sibẹ lati ilu bi mẹnkẹlọgọta.

Ọgbẹni David Awofisan ti o jẹ aṣoju Araba Ile-ifẹ ni o ṣe alaga, Ọgbẹni G. A. Odumade ni o ka iwe ipade ti o kọja, gbogbo ile si gba A... adura ni awọn ṣe fun dide si Nigeria Ọba Obinrin pẹlu ọkọ rẹ lati ilu Oyinbo wipe ki awọn de ni alafia ki wọn si lọ du awọn ni alafia.

Odu-ifa ti awọn fi ṣe Adura ni ni a npe ni "Oluruọọn tite", Ọgbẹni Orisasona ti o jẹ olori ye Seriki Awo ti ilu Oshogbo ni o ṣe adura na awọn si mu da gbogbo enia l'oju wipe t'ọwọ t'ẹsẹ ni wọn yio fi gba Alayeluwa Ọba Obinrin ilu Gesi ati ọkọ rẹ ni alejo.

ILE ẸKỌ IFA

Lẹhinti ọpọlọpọ enia ti sọrọ ipade gba lati da ile ẹkọ Ifa silẹ ati ile isin Ifa pẹlu. Ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ sọ wipe Ifa l'oni o o ọsẹ sugbọn Jesu l'oni Satide. bi ti a mọ A ti pe awọn yio bẹ Ijọba Iwọ-orun ki wọn gbe imọ Ifa s'oke ni agbegbe Iwọ-orun.

Ọgbẹni Abiobola Savage ti o wa lati Eko gba gbogbo ipade ni iyanju wipe ki nwọn jẹgiri si ẹkọ Ifa nitoripe gbogbo ọla Ifa ṣe ndieku ko si dara ki awọn Baba wa ma gbe wọn lọ s'ọrun lai ko a fi kọ awọn aromọdọmọ wọn.

ki a to mu ipade de opin Ọgbẹni gbadebọ Dosunmu ti iṣe Olidasilẹ ile isin enia dudu (Ijọ Ọrunmila) ni a yan si ipo akọwe Agba fun gbogbo Ijọ Babalawo lẹhin eyi ni faaji wa bẹrẹ jijẹ ati mimu npe arawọn raeṣẹ faaji a ṣe di ọganjọ oru ni gbogbo ilu to wa ni Iwọ-orun ni o fi aṣoju ranṣẹ wa si ipade yi, a si fi ipade ti oṣu March 1956 silu Abeokuta,

## Alo o. Alo

Agbo'lẹ gbẹ'lẹ akun oniṣegun rugudu ti on ti ad...

ITUMỌ RẸ

Iṣu ni

## The Ministry Of Education, Western Region

VACANCY FOR REGIONAL LIBRARIAN.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Regional Librarian in the Regional Headquaters.

2. SALARY: (a) For pensionable officers Scale A; £624 x 36 - £696 £804 x 42 -£1, 140 x 48 - £1,380.

(b) For Contract officers: As for pensionable officers plus 10o/o basic salary plus gratuity subject to any Revision that may be made by Regional Government in the light of 1954/55 Salaries revision for Contract Officers

3. QUALIFICATIONS: Candidates must possess either an academic degree and / or professional qualification (LFA) plus suitable experience.

4. DUTIES: Successfull candidates will be required to advise on the planning and organisation of Library Services in the Western Region, take charge of Central Library to built in Ibadan within the next two years and supervise Local Authority and Community Reading Room, and such other duties as the Head of Department may assign to him.

5. OTHER CONDITIONS OF SERVICE:

(1) If an expatriate on first appointment an Outfit allowance of £60 is payable.

(2) The Provision of Government Quarters, where applicable is subject to the payment of rent at 8 1/3 of basic salary.

METHOD OF APPLICATION: In Nigeria: Applications from candidates not in Government Service should be completed in duplicate on the prescribed form obtainable from the Secretary of any of the Regional or Federal Public Service Commissions.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Heads of Departments and be accompanied by copies of Confidential Reports for the last three years and a covering letter wherever possible containing special comments that may prove of value in assessing the suitability of the candidate for the post applied for.

In the United Kingdom: Applications should be competed in duplicate on the prescribed form obtainable from the office of the Commissioner of the Western Region of Nigeria, 18, Grosvenor Gardens, London, S. W. 1, and submitted through the Liaison Officer to reach him by December 26, 1955.

All applications should reach the office of the Director of Recruitment, Public Service Commission, Western Region of Nigeria Ibadan not later than 2nd January, 1956.

## Bi Taiwo Ba Soko Kehinde, Ko Lese

Obinrin Egba kan, ara Abeokuta ti a npe ni Jọ-ọda (Ọjọ yi o da) bi ọmọ Ibeji, ọkan jẹ ọkunrin, ekeji jẹ obinrin. Gẹrẹ ti o bimọ tan ni Jọ-ọda bẹrẹ amodi ko si omi nino ọmu rẹ. Iya Ọkọ rẹ gba eyi obinrin lati ma tọ, Aburo rẹ ti o jẹ ọmọ iya kanna pẹlu Jọ-ọda ti o ṣẹṣẹ bimọ tan gba eyi keji lati ma tọ pẹlu ọmọ tirẹ.

Laipẹ aburo Jọ-ọda lọ si Oke okun. Lẹhin ọdun mẹdogun Jọ-ọda pẹlu ọmọ rẹ obinrin ti wa si Eko pẹlu ọkọ rẹ ti o nṣẹ baba ọmọ na. Irohin lọ siwaju wipe Jọ-Ọda gburo ọmọ rẹ ati aburo rẹ wipe nwọn wa ni ilu kan ti a npe ni Ọda.

Opopo kanṣoṣo lo mbẹ ni Ọda, ẹniti nwọn walọ wa ni ibẹrẹ ati wọ ilu, Jọ-ọda de si opin ilu o fi orukọ aburo rẹ welọ, ko si ẹniti o mọ. Ṣugbọn awọn ọmọ iya meji Taiwo ati Kẹhinde ti nri ara wọn, nwọn sọrọ pọ tobẹ ti o fi di oyun.

Nigbati Jọọda ri oyun lara ọmọ rẹ, o bere tani loyun o si daruko Taiwo, nwọn ni ko pe wa, nigbati Taiwo de, ko mọ iya rẹ, iya rẹ ko si mọ. Nwọn bere tani loyun o si dahun pe on ni. Nwọn ni ko pe iya rẹ wa.

Taiwo rohin fun alagbatọ rẹ pe, on fun ọmọ Yoruba kan loyun iya rẹ ni ki ẹ fi oju kan on. Nigbati Jọ-ọda fi oju kan aburo rẹ, nṣe ni akara tu sepo. Agbaregbabọ nwọn fi ọrọ na lọ Alufa Sọṣi, nwọn si dahun pe ko si ẹṣẹ nibẹ, ni wọn bi Anọbi Lutu ti Iṣe ọkọ awọn ọmọ rẹ, nitori na ni irun Jẹbus ṣe di oluwọ fun ọmọ Israeli nigbati nwọn n'ọ silẹ Keniani, Ọlọrun paṣẹ pe ki ẹni-kẹni maṣe fọwọ kan wọn

## Oba Kaleshuwe ti Apoi Okitipupa be Eko wo

Alaiyeluwa Ọba S. Adetimẹhin Ọladiran I Kaleshuwe Apoi Okitipupa wa bẹ ilu Eko wo l'ọsẹ tokọja, o si pada si ilu rẹ ni ọjọ Wednesday ọsẹ na.

Awọn ẹgbẹ Igbobini ni o gba ni alejo, ile Ọgbẹni D. L. Omoyẹni, Ọga onişowo Gẹdu ni o wọ si ni 60, Griffith Street, Ebute-metta, Alaiyeluwa Ọba yi bẹ ọpọlọpọ ibi pataki pataki wo, bi ile itọju awọn ẹranko ti Ọgbẹni Biney ati ile ọti Bia ti Iganmu l'ọna Apapa

Alaiyeluwa Ọba na tun l'ọ ṣe isin idupẹ ni ọjọ ọse ni 'le isin awọn U.N.A Ebute Mẹta, Ọgbẹni A. R. Smith si fi apejẹ nla kan bu ọla fun ọba na ni ile rẹ 2, Market Street, Ebute-Metta.

Ni aṣalẹ ọjọ lilọ rẹ ku ọla ni awọn ẹgbẹ Igbobini ti Eko ati Ebute-mẹta ṣe ẹyẹ fun ni Gbọngan Liṣabi ni Ebute metta, awọn oloye ti o ba Ọba wa ni Oloye Arogbo ti Shabomi, Oloye Ọdọfin ti Idotu, oloye Ajanna ti Igbobini, oloye Gbajọbi ti Shabomi ati Ọgbẹni paul. ọla Jọshua

E o ba'le ni ire o

No. 73/S.2/Vol. V/944.

# PUBLIC NOTICE

The Director of Education, Western Region, wishes Mr. A.O. Oniyitan, C. 1/750, formerly a teacher at St. Andrew's School, Ipaja, Colony, to notify him of his present address.

The Director is anxious to communicate with Mr Oniyitan in connection with matters pending before the Teachers' Council constituted under the Western Region Education Law, 1954 and which will have to proceed in his absence if he cannot be found.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS



## Egbogi ti Colgate ti a fi nfo ehin nikansoso lo daju ti o si nmu ireti wa fun opo enia

LOSAN ATI LORU KO NJE KI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol

Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje losan t'oru.





OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun ehin te, awon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyiti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo

Sodium N. Lauroyl Sarcosinate

SAME FAMILIAR PACKAGE




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki eon re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

**O dara t'osan t'oru ko njeki ehin enia baje.**

## Oloye Sanusi Agbabiaka D'ologbe

EKO Alagba Oloye Sanusi Aghagbaki ti iṣe baba fun Ọgbẹni A. S.E. Agbabiaka ni o salaisi ni ọjọ Tuesday ti iṣe Ogun'jọ oṣu December, 1955, ni ile rẹ ni 4, Viceat Street, l'Eko.

Ọgbẹni A S.E. Agbabiaka ti de si Eko lati bi ọsẹ kan lati wọ Ọkọ lọ si ilu Oyinbo fun imọ eko iṣẹ Oga fun awọn Ọlọpa, ṣugbọn bi o ti wọkọ ni Apapa ti awọn ojulumọ si ki wipe odigb'ose, pipada de ile awọn ero ti o sin wọkọ, oku baba rẹ ni nwọn de ba nile.

Ni irọlẹ ọjọ Alaruba, (Wednesday) ọjọ kọkanlelogun oṣu December, 1955, ni nwọn sin'ku alagba Oloye Sanusi Agbabiaka ni Itẹ-Oku, Ikoyi.

A ki gbogbo ẹbi ati awọn ọmọ Oloku, ku aṣẹhinde, ki Ọlọrun gba baba si afẹfẹ rere.

## OLU EPE



Aworan inu iwa yi niti Ọlọla Olu Ẹpẹ ti awọn ẹgbẹ Arowoṣọla nmura lati ṣe ẹyẹ fun nigbati o ba nlọ pade Ọba Obirin ilu Oyinbo ati ọkọ rẹ ti yio wa si Nigeria yi ninu ọdun ti o mbọ yi

A lọ yio dara, abọ yio suewọn o.

# E KU EWU ODUN O!

Ẹ ku ewu ọdun, ẹmi yio ṣe ọpọlọpọ rẹ ki Oluwa Olodumare jẹki ire kari gbogbo wa ninu ọdun yi, ki Jesu Olugbala ti a bi si aiye ni ayajọ Christmas ṣe alatilẹhin fun wa fun ọdun yi, ninu itẹsiwaju ninu Oluwa ati iṣẹ ọwọ wa ṣiṣe.

Michael Awoyale
28, Idunmagbo Avenue
Lagos

Mo ki gbogbo ẹlẹgbẹ Christian Ẹ ku imura ọdun Keresimesi, eyi to jẹ pe a bi Olugbala fun wa. Gẹgẹbi onigbagbọ, o yẹ ki a mura lati ri wipe a parawa mọ ninu ẹṣẹ, ṣaju atilẹhin ọdun na. Mo ki ọrẹ ojulumọ ati olutaja ati alabara, Ẹ ku imura ọdun. Olodumare jẹki a fi ayọ ṣe

A. A. Ajiboye
26. Idunmagbo Avenue
Lagos

Mo ki olotu iwe Eleti-Ọfẹ, mo si ki awọn enia wa l'ọkunrin ati l'obinrin fun ajabọ ti ọdun yi, pataki awọn onibara wa ni Eko ati gbogbo ilu miran. Ẹ ku iyedun, aṣeyi ṣamodun.

H. A Oyinloye,
6, Balogun Street West,
Lagos

Mo ki gbogbo onigbagbọ ti mbẹ lori ilẹ aiye fun ọdun Keresimesi, pataki awọn alabara wa ti mbẹ ni gbogbo ilẹ karọ-ojire. Mo ki ọmọde, ni agba ẹgbẹ ọkan mimọ ululọ ti Jesu gẹgẹbi Ọlọrun alaiye boti mu wa di amọdun

Ọlọrun jẹki anipin, ki ama padanu ẹmi wa.
Ki ọmọde ati agba mura si ẹsin. O yẹ ki a wa ọna ẹsin gẹgẹbi Bibeli

Simeoni Oyebanji

Alaga Ẹgbẹ ọkan mimọ ti Jesu

Fun ọdun titun to ṣe oju ẹmi, mo fi eyi ki gbogbo awọn enia jake-jado gbogbo ilẹ Nigeria wipe ẹ ku ọdun, ni pataka awọn ọrẹ ati ojulumọ, papa mo ki gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Ilọsiwaju Oro (O.P.U.). Ki Oluwa fi ọpọlọpọ ọdun ṣoju ẹmi wa. Mo si tun dupẹ lọwọ Olotu fun iṣẹ ribi-ribi ti nwọn nṣe lati wa ilọsiwaju fun ilu Nigeria.

A. A. Awodiji,
Chairman Oro Progressive Union.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun to ṣọwa la ọdun ja kasi fi ayọ ati alafia lo ọdun t'ama bọsi. Ki ore ọfẹ Ọlọrun ko ma wa pelu wa. Ki idawọle iṣẹ wa ki o jẹ iyọsi rere.

P. A. Bamigbe
9, Church Street
Lagos.

Ọsẹ yi ni Iwọle ọdun Keresimesi, ọdun Olowo, gẹgẹbi ọrọ orin awọn enia wa. Mo fi wosika mi yi ki gbogbo ẹnyin enia mi, ẹnyin ọrẹ mi ati ojulumọ mi, wipe, Ẹ ku ewu ọdun.

Ki Baba Oluṣọni rere, maṣai fi iṣọ Rẹ ṣọ gbogbo wa, ki o si fun wa ni alafia ati ẹmi im'ore fun Oluwa Olodumare - Amin.

Abudul Rahman Subair
36, Idita Street,
Lagos.

### Dodokin Omu Agba

Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ ti di dodokin-ọmu-agba, ari ma le yẹ'ju, akatunka fun gbogbo enia.

Bi o ba fẹ ki ọja rẹ ta, wa polowo sinu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ.




Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone [illegible]